FUJAH/Vol. 1, No. 1 | June 2024 | Pages 154–162

# FÍÌMÙ YORÙBÁ: ỌNÀ LÁTI TÁN ÌṢÒRO ORÍLẸ̀-ÈDÈ FÚN ÌDÀGBÀSÓKÈ.

**IBRAHIM** Wahab Adegbayi Ph. D
Department of Yorùbá Studies,
Tai Solarin University of Education,
Ijebu-ode, Nigeria.
adegbayiwahab@gmail.com
08055215824

SULAIMAN Fatai , Department of Yorùbá Studies, Tai Solarin University of Education, Ijebu-ode, Nigeria. olaitonolaide2018@gmail.com 07063900080

**Àṣamọ̀**

*Ṣáájú kí àwọn òyìnbó tó dé sí Àwùjọ adúláwọ̀, pàápàá orílè-èdè Naijiria eré-oníṣẹ́ jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì tí àwùjọ ń gbà wá ojútùú sí àwọn ìṣòro tí àwùjọ tàbí ẹ̀dá àwùjọ ń kojú. Láàárín àwọn Yorùbá, eégún aláré àti àwọn ọdún ìbílẹ̀ ní tíátà tí wọ́n ń lò láti ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìdánilárayá láwùjọ wọn. Àwọn àgbékalẹ̀ méjèèjì yìí ni ọ̀nà pàtàkì tí àwọn àwùjọ máa ń fi mọ ohun tí ó ń lọ nílùú. Àwọn òṣèré eégún aláré máa ń ṣe àgbékalẹ̀ tí ó ní ṣe pẹ̀lú pípé àkíyèsí àwọn ènìyàn àwùjọ sì ọ̀rọ̀ tó ń lọ, kí àwọn tí ọ̀rọ̀ kan lè kó ara wọn ní ìjánu. Ojúṣe àwọn aláré yìí ni láti lè se ìtónisona fún àwọn onwòran, tí wọn jẹ ara ilu kí ilosiwaju lè bá eda kọ̀ọ̀kan àti ìlú wọn, èyí tí yóò jẹ ìgbéga fún orílè-èdè. Pépà yìí ṣe àmúlò àwọn fíìmù Àgbéléwò Yorùbá bíi mélòó kan, láti wo ọ̀nà tí àwọn Oníṣẹ́ fíìmù tàbí àwọn àjọ òṣèré ń gbà wá ojútùú sì àwọn ìṣòro tí àwùjọ ń koju, kí ìdàgbàsókè lè bá irú àwùjọ bẹẹ. A gbìyànjú láti wo oríṣìíríṣìí fíìmù àti lé wo ọ̀nà tí wọ́n ń gbà pé àkíyèsí àwọn ènìyàn àwùjọ sì ọ̀nà tí orílẹ̀ èdè yìí Léfi bo nínú ìdààmú, ipayin keke tí a ń koju báyìí. Oríṣìíríṣìí fíìmù tí ó nise pẹ̀lú ona ati lè yanjú ìṣòro orílè èdè yìí là ń gbìyànjú láti wo, bákan náà ni a fi ọ̀rọ̀ wa àwọn onworan tàbí ara ilu lẹ́nu wo láti wo ipa fíìmù lórí wọn, lójú ọ̀nà àti wá ojútùú ìṣòro aìrìná, airilo, ọ̀wọ́n gógó oúnjẹ, igbenipa, ijinigbe, olè jíjà, yíyí ìbò, òògun olóró,àsìlò oogun àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Pépà yìí fihan pe fiimu lè tán ìṣòro tí orílè èdè yìí ń kojú, ti àwọn onworan bá ń fi ọkàn bá àwọn àgbékalẹ̀ yìí lọ, tí wọn sì ń ìṣàmúlò àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ inú àwọn fọnrán tí wọ́n wo fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìdániláraya, lái kan máa wo fíìmù fún awẹ́wá tàbí ìgbádùn nìkan. Ó hàn gbangba pé, lítíréṣọ̀ tí àwọn ará ìlú feran lóòrè koore ni fíìmù jẹ́. Iṣẹ́ yìí fihàn pé tí àwọn ènìyàn bá lè kópa pàtàkì nínú àtúnṣe orílẹ̀ èdè, tí wọ́n bá ń sàmúlò ẹ̀kọ́ tí àwọn onífíìmù fẹ́ kí wọn kọ nínú awon àgbékalẹ̀ wọn.  Gbogbo ìwàgúnlẹ̀ fíìmù Yorùbá máa ń fi hàn pé, wọn fẹ́ kí àwọn ènìyàn máa kópa tí ó yanranti lórí ìdàgbàsókè àwùjọ wọn.*

**Abstract**

This study examines how Yoruba films address societal issues, using them as a medium to educate and enlighten the community. The study also investigates how the audience perceives these films,

whether as a means of entertainment or education. Furthermore, it explores the impact of these films on the audience and how they contribute to the development of the community and the country at large. The study reveals that films can be an effective tool for addressing societal issues. The study also shows that filmmakers often use their works to draw attention to pressing issues in the community and encourage positive change. The study recomends that filmmakers should endeavour to use their works to address societal issues and promote positive change. The study concludes that if people can learn from the lessons portrayed in these films, it will lead to positive development in the community.

**Keywords**: Yoruba films, entertainment, audience, education, social issues.

**ÌFÁÁRÀ**

Fíìmù Yorùbá jẹ́ ọ̀kan lára ọ̀nà tí wọ́n fi ń bá àwọn ará ìlú sọ̀rọ̀. Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ pàtàkì ni wọn máa ń fi àwọn eré tí wọ́n ká sínú fọ́nrán ṣe fún àwọn onworan tí wọ́n jẹ́ ara ìlú tàbí ènìyàn àwùjọ. (Adélékè 1995). Fíìmù gbọ́dọ̀ ni ise pàtàkì tí wọ́n fẹ́ fi rán sí àwọn ènìyàn àwùjọ (Adagbada 2005:18) láti ọdún 1976 tí fíìmù Yorùbá ti bẹ̀rẹ̀ sí ì gun orí àtẹ ni ó ti hàn gbangba pé, wọn fẹ́ máa ló ò láti fi máa tọ́ àwọn ará ìlú sọ́nà. Ìdàgbàsókè tí ó dé bí eré Oníṣẹ́ yìí, jẹ́ kí àwùjọ máa dàgbà, nítorí pé, fíìmù jẹ́ iṣẹ́ ọnà kan pàtàkì fi àwọn ènìyàn àwùjọ nífẹ̀ẹ́ sí. Lóòrè-kóòrè ni wọ́n máa ń wò ó, bí wọn sẹ́ ń wò ó nínú fọ́nrán ni wọn ń wò ó lórí àwọn èrò fóònù alágbèeká wọn, èyí jẹ́ ki ó rọrùn láti máa ṣe. Àwọn ọ̀ṣèré rí i pé àwọn ènìyàn àwùjọ tẹ́wọ́ gba fíìmù, èyí sì jẹ́ ọ̀nà pàtàkì láti máa rí owó, tí irú fíìmù bẹ́ẹ̀ bá jẹ́ èyí tí àwùjọ tẹ́wọ́ gba. Àwọn fíìmù Yorùbá gbọ́dọ̀ ṣe àtúnṣe orílẹ̀ èdè. Nípa ṣíṣe èyí, àwùjọ yóò máa tẹ́síwajú, ìdàgbàsókè tí ó lóòòrìn yóò sì fi ojú hàn. Fíìmù tí ó wúlò, tí ó sì ní ẹ̀kọ́ pàtàkì tí ó fẹ́ kó àwọn ará ìlú ni a gbọ́dọ̀ máa fi ọwọ́ sí, pàápàá àjọ alábòójútó Ẹ̀ka fíìmù ni orílẹ̀ èdè wa. Tí àwọn ọ̀ṣèré bá ń ló fíìmù wọn fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó yẹ, yóò máa tọ́ka sí ìdánilárayá tí ó gbogbon. A gbọ́dọ̀ máa fi ọkàn bá fíìmù tí a bá ń wo lọ, kí a sì máa di ìdánilẹ́kọ̀ọ́ inú rẹ̀ mú, pàápàá èyí tí yóò wúlò fún ìdàgbàsókè orílẹ̀ èdè.

**FÍÌMÙ YORÙBÁ**

Fíìmù sẹ̀lúlọ́ọ̀ìdi ni ẹ̀yà fíìmù tí ó kọ́kọ́ wo àwùjọ Yorùbá. Èyí ni alákààsagba, tí wọn máa ń fi èrò gbé jáde láti ara ògiri fún àwọn onworan. Ìdàgbàsókè tí a lè fi ojú rí ní o débi fíìmù Yorùbá ni ọdún 1976, tí ọlá Balogun gbé fíìmù Yorùbá àkọ́kọ́ jáde, tí ó pe àkọlé rẹ ni. O ajani ogún. Ibrahim 2022, adeleke 1995, adagbada 2004. Láti ọdún 1976 yìí ni fíìmù ni èdè Yorùbá ti wá gbìn àyà, tí àwọn ènìyàn sí jẹ́wọ́gbàá. Ibrahim 2022:48 ó hàn gbangba pé fíìmù elédè Yorùbá ni iṣẹ́ pàtàkì tí wọ́n fí fẹ jẹ́ láwùjọ, pàápàá ni orílẹ̀ èdè Nàìjíríà. Adeleke 2020. Moses olaiya gbé fíìmù Yorùbá kan jáde tú ọ pé ní mosebolatan ni odun 1978. Odun 1978 yìí kan náà ni afolayan gbé fíìmù ìyá ni wúrà jáde. Láàárín ọdún 1978 sì ọdún 1980ni àwọn fíìmù bí taxi driver, jayesimi, aropin ń teniyan àti Àyàǹmọ́ láti ọwọ Ògúǹdé jáde. Ìfẹ́ tí àwọn omo Yorùbá bẹ̀rẹ̀ si ni fihàn sì fíìmù Àgbéléwò Yorùbá, ko se é fi ọwọ́ rọ́ sẹ́yìn làwọn àsìkò yìí. Odun 1991 ni ọla Balogun tún gbé fíìmù torí adé jáde. Odun 1990 ni Kọ́lá olatunde gbé fíìmù tìrẹ tí ó pè àkọlé rẹ ni igi dá

jáde, alamu 2001:41. Ọ̀ṣọ́ Dáramọ́lá gbé *Ajá Dúdú* jáde ní ọdún 1991 láti ọwọ Ẹbun Oloyede. Láti àsìkò yìí ni fíìmù Yorùbá wá ń jáde lóòrè koore. Ibrahim (2022:48). Àwọn ẹ̀yà òṣèré onilana Ògúǹdé wá gbajumọ Ṣiṣẹ́ fíìmù Àgbéléwò láti ọdún 1990,fun ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìdánilárayá èyí tí yóò wúlò fún ìdàgbàsókè àwùjọ wọn. Àwọn iléése fíìmù bí Aládé arómiré, Jide kosoko, Bayo films, Cooperate Pictures àti àwọn iléése fíìmù bẹ̀rẹ̀ sii gbé fíìmù jáde pẹ̀lú èdè Yorùbá, èyí tí ó ń fi àṣà àti ìṣe àwùjọ Yorùbá hàn, pẹ̀lú ìhà tí ó yẹ kí àwọn Yorùbá kọ sí Orílẹ̀-èdè wọn, kí ìdàgbàsókè ó lè fi ojú hàn. Mobọ́lájì (2000).

Oríṣìíríṣìí fíìmù Yorùbá ni àwọn ilé iṣẹ́ onífíìmù bẹ̀rẹ̀ sii gbé jáde fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́ mainfrane tí tunde Kelani jẹ́ agbatẹru rẹ jẹ ọkan gbòógì tí a lè tọ́ka sí pé ó ní èrò tí ó dára láti rí i pé àwọn fíìmù wọn ń kọ́ àwọn ènìyàn kẹ́kọ̀ọ́ nípa kíkópa lórí àti wá ojútùú sì ìṣòro yọnu tí àwùjọ lè máa kojú. Adagbada (2024). Ohun iwuri ni ó jẹ́ pé, àwọn òṣèré Yorùbá ni àfojúsùn nípa èrè tí wọ́n ń gbé jáde, wọn máa ń dójú ìṣe wọn kò àwọn Ìṣèlẹ̀ Àwùjọ, kí àwọn òǹwòran lè mọ ohun tí ó ń lọ láwùjọ àti ọ̀nà láti kópa tí ó yeye. Àwọn fíìmù bí saworoide, tí olúwa nílẹ̀, agogo eewọ, àbẹ̀rú, narrow path àti beebee lọ ní o fi idi rẹ múlẹ̀ pé àwọn fíìmù elédè Yorùbá ni ipa pàtàkì tí wọ́n ń kó lórí ìdàgbàsókè àwùjọ. Apena (2023).

## ÈRÒ ÀWỌN ONÍMỌ̀ LÓRÍ ÌDÀGBÀSÓKÈ.

Ìdàgbàsókè ni ọ̀nà tí nǹkan bá yí padà sí rere fún ìlọsíwájú àti àmúgbòòrò fún ẹnìkan tàbí àgbáríjọ àwọn ènìyàn kan. Ojú tí àwọn onímọ̀ fi ní ìdàgbàsókè yàtọ̀ sí ara wọn. Ìlànà tí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn onímọ̀ tí wọ́n ṣe àyẹ̀wò lórí ìdàgbàsókè yàtọ̀ sí ara wọn. A rí àwọn onímọ̀ tí wọ́n gbajúmọ̀ ìdàgbàsókè àwùjọ, oyè tíwọ́n ní í ṣe pẹ̀lú ìdàgbàsókè ètò ìṣèlú, ètò ọ̀rọ̀ ajé, okoowo, esin, Ìbágbépọ̀ àti àjọṣe. Ní ti àwọn onímọ̀ kan, ó wọn rí ìdàgbàsókè gẹ́gẹ́ bí ohun pàtàkì tó n mú ìlọsíwájú àti àyípadà rere bá ohun kan. Lára nnkan bẹ̀ẹ̀ ni ewéko, ẹranko, odo, kòkòrò, ohun ogbin, ẹ̀yà ara ènìyàn àti àwọn ohun tí ó ní í ṣe pẹ̀lú ìmọ̀ sayensi. Seer (1999), Fẹ́rànmi (2001), Omolewa (2002) seer ni tìrẹ gbà pé ìdàgbàsókè ní í ṣe pẹ̀lú àkóónú àwọn ohun mìíràn tí ó ju ètò ọ̀rọ̀ ayé lórí ṣùgbọ́n, ó tún ní í ṣe pẹ̀lú ipò tí àwọn ènìyàn orílẹ̀-èdè wa nípa pípèsè àwọn ohun jíjẹ tí ó pọ̀jù òwò àti iṣẹ́ ṣíṣe, ìpawówọlé tí kò dọ́gba mọ́. Ohun tí onímọ̀ yìí ń sọ ni pé kì í ṣe ètò ọrọ̀ ajé nìkan ló ń mú ìdàgbàsókè bá àwùjọ, ṣùgbọ́n ètò ọrọ̀ ajé gan-an ni òpómúléró nínú ètò tó ń mú ìdàgbàsókè bá àwùjọ. Feranmi (2000:174) ní tirè gbà pé ìdàgbàsókè fúnra rẹ̀ lé è jẹ́, tí ìmọ̀ èrò tàbí nígbà mìíràn kí ó jẹ́ ti ìṣèlú, Ìbágbépọ̀ - ajẹmọ́ - àṣà, ètò ẹ̀kọ́ èsìn tàbí ètò ọrọ̀ ajé. ohun tí ó ń tọ́ka sí ni pé kò sí ibi tí ìdàgbàsókè kò ti lè wáyé láwùjọ.

Ọmọlewù (2002:85) sọ ní tirẹ̀ pé, gbogbo ìlànà tí ìgbé ayé yóò fi rọrùn fún àwọn ẹ̀dá àwùjọ ni a lè tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ìdàgbàsókè

Ìdàgbàsókè ni ọ̀nà tí àyípadà rere gbà bá àwùjọ, èyí tí ó fi ojú hàn lára igbé ayé ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan. Akóredé (2008:54) ní tirẹ̀ gbà pé àyípadà gan-an ni a lè pè é ní Láríjà ìdàgbàsókè. Ó tọ́ka pé kí ètò ẹ̀kọ́ tó lè ní ìdàgbàsókè, àyípadà gbọ́dọ̀ dé bá kọ̀ríkúlọ́ọ̀mù tí wọ́n ń lò láti fún ètò ẹ̀kọ́ bẹ̀ẹ̀.

Popoola (2008:29) náà sọ pé ìdàgbàsókè ni ìyípadà tí ó dé bá àwùjọ lórí ètò - ọrọ̀ - ajé, Ìṣèlú àti àwọn ọ̀nà ìgbé - ayé gbogbo.

Hassan (2009 :155) ní tirè gbà pé kí a tó lè gbà pé àwùjọ ní ìdàgbàsókè, àwọn ènìyàn inú àwùjọ bẹ́ẹ̀ mójú tó abala ètò ìṣèlú wọn dáadáa. Ó hàn pé ọ̀rọ̀ ìdàgbàsókè kò ṣe é fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú tí a bá fẹ́ ki ètò ìṣèlú kẹ́sẹjárí ni ìlú tàbí orílẹ̀ èdè. Ọwọ́ yẹpẹrẹ kò ṣe é fi mú Ìdàgbàsókè, tí a bá fẹ́ kí tolórí tẹlẹ́mù, ó fi ẹdọ̀ lórí òrónrò láwùjọ, pàápàá ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà.

**ÀWỌN ATỌ́KA ÌDÀGBÀSÓKÈ LÁWÙJỌ.**

Kí á tó lè sọ pé ìdàgbàsókè dé bá ẹ̀dá àwùjọ kọ̀ọ̀kan àti àwùjọ fúnra rẹ̀, ìfọ̀kànbalẹ̀ gbọ́dọ̀ wáyé láwùjọ Adepoju (2009).

**Ìdàgbàsókè àwùjọ**

Àwùjọ ṣe pàtàkì tí a bá ń sọ̀rọ̀ ìdàgbàsókè. Láì jẹ́ pé àwùjọ ni ìlọsíwájú, ẹ̀dá àwùjọ kò le ní ìfọ̀kànbalẹ̀. Ìwúrí ni ó máa ń jẹ́ fún ẹni tí ó bá rí i pé àwùjọ ń tẹ̀síwájú nípa ètò ọrọ̀ ajé, ètò ẹ̀kọ́, Ìbágbépọ̀, ìmọ̀ èrò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. ìgbà tí a bá rí ìdàgbàsókè lára ẹ̀dá àwùjọ ni a lè gbà pé àṣeyọrí wà láwùjọ.

**Ìdàgbàsókè ènìyàn**

láì sí ìdàgbàsókè àwọn ènìyàn àwùjọ kò sí ohun tí a gbọ́dọ̀ tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ìdàgbàsókè láwùjọ kan. Omoregbe (1990:197) Ó tọ́ka pé orílẹ̀-ede kan tó lè máa tọ́ka pé òhun ni ìlọsíwájú, àwọn ènìyàn inú rẹ̀ gbọ́dọ̀ ní ìlọsíwájú tí ó fi ojú hàn. Lára àwọn ènìyàn àwùjọ gangan ni ìdàgbàsókè tí máa ń wáyé tí yóò ṣàfihàn àwùjọ kan tàbí òmíràn pé ó ń lọ síwájú lóòrè kóòre.

**Ìdàgbàsókè ìwà**

Adefarasin 2014 fihàn pé ìwà àwọn ẹ̀dá àwùjọ bá ṣe rí, ní irú àwùjọ bẹ́ẹ̀ yóò rí. Iwà ṣe pàtàkì láwùjọ ẹ̀dá, ìṣesí, àti ìhùwàsí àti ìbáṣepọ̀ àwọn ẹ̀dá máa ń ṣàfihàn bí àwùjọ wọn ṣe ń lọ síwájú

**Ìdàgbàsókè ètò ọ̀rọ̀ ajé**

Ètò ọ̀rọ̀ ajé jẹ́ òté mìíràn tí a fi ń pe ìdàgbàsókè láwùjọ wá ní àwùjọ kan. Láì sí ìdàgbàsókè ètò ọ̀rọ̀ ajé a ó lè sọ pé ìlọsíwájú wà ní àwùjọ bẹ́ẹ̀. Ètò ọ̀rọ̀ ajé ni ó máa ń ṣe atọ́nà bí ìlú tàbí orílè èdè kọ̀ọ̀kan ṣé ń gòkè lágbàáyé.

**Ìdàgbàsókè ètò ẹ̀kọ́**

ohun mìíràn tí ó máa ń ṣokùnfà ìdàgbàsókè láwùjọ ni ètò ẹ̀kọ́. Irú ẹ̀kọ́ àti ìlapa ètò ẹ̀kọ́ tí ó bá wà lára àwọn ènìyàn àwùjọ máa ń ṣokùnfà irú ìdàgbàsókè tí yóò wá. Ètò ẹ̀kọ́ ni ó máa ń tọ́ka sí ìgbéga àwùjọ kọ̀ọ̀kan. Àwùjọ kò lè dàgbàsókè lai jẹ́ pé wọn rí í lára àwọn ènìyàn, ìhà, ètò ọ̀rọ̀ ajé àti àwọn ohun amáyédẹrùn gbogbo. adefarasin 2015:10.

**IPA ÀTI IPÒ FÍÌMÙ YORÙBÁ NÍNÚ ÌDÀGBÀSÓKÈ ÀWÙJỌ**

Fíìmù Yorùbá máa ń jẹ́ ọ̀kan pàtàkì tí àwọn ènìyàn àwùjọ ń gbà kọ ẹ̀kọ́ nípa àwùjọ wọn. Àwùjọ gan-an ni fíìmù tí ń jáde, àwọn orísìírísìí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ni àwọn òǹsefíìmù máa ń ṣe àgbékalẹ̀ láti fi ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìdánilárayá fún àwọn ènìyàn àwùjọ. Àṣà àwùjọ ni ó máa ń fi ojú hàn nínu fíìmù káríayé. Àwùjọ tí wọ́n bá ń gbé fíìmù jáde fún ní wón máa ń tọ́ka sí ọ̀nà tàbí ìwà àti ìṣe (bàraku) àwọn ènìyàn bẹ́ẹ̀. Àwùjọ gan-an ni omi ọgbọ́n fún fíìmù elédè Yorùbá. Fíìmù ti jẹ́ kí àwùjọ ní ìlọsíwájú látàrí ọ̀nà tí wọ́n ń gbà ṣe iṣẹ́ yìí, àti pé ọ̀nà òkòówò pàtàkì ni fíìmù jẹ́ fún àwùjọ báyìí. Adágbádá (2012:101).

Fíìmù gbọ́dọ̀ lè máa tọ́ àwọn ènìyàn àwùjọ sọ́nà. Awon àgbékalẹ̀ onifiimu gbọ́dọ̀ jẹ́ èyí tí yóò mú ìlọsíwájú bá àwọn òǹwòran. Ìlọsíwájú àwùjọ ni ó gbọ́dọ̀ jẹ́ àwọn òǹsefíìmù lógún. Fíìmù ló ń kọ àwọn ènìyàn àwùjọ lẹ́kọ̀ọ́ nípa àwùjọ àti ipa tí ó yẹ ki wọn kó láwùjọ kareem (2015.174). Tí kò bá ṣe fíìmù

ọ̀pọ̀lọpọ̀ èniyàn lè máa ní ayé nípa àṣà àti ìṣe àwùjọ wọn, ọ̀nà ìgbé ayé àwùjọ, ètò ìṣèlú àti àwọn Ìṣèlẹ̀ Àwùjọ lóríṣìírìṣìí. Àgbékalẹ̀ tí àwọn onífíìmù máa ń ṣe wà fún àwọn èniyàn àwùjọ. Adélékè (1995.201) àwọn òǹwòran jẹ́ èniyàn àwùjọ tí wọ́n fẹ mọ ohun tí ó ń lọ láyìká wọn. Ìdàgbàsókè tí ó lóòòrìn ni fíìmù tí mú bá àwùjọ wà báyìí. Ipa pàtàkì ni fíìmù elédè Yorùbá ń kó lórí àwùjọ wọn, pàápàá orílè-èdè. Tí kò bá si iru fọ́nrán lítíréṣọ̀ yìí, ó lè nira láti jẹ́ kí àwọn ọmọ orílẹ̀-èdè ní ipa pàtàkì tí wọ́n lè kó lórí ìdàgbàsókè àwùjọ wọn (Apènà, 2023)

Oríṣìírìṣìí fíìmù Yorùbá ni ó ń ṣe ìsínijẹ nípa àwùjọ Nàìjíríà. Ọ̀pọ̀ àwọn fíìmù yìí ni ó ń atọ́ka ìdàgbàsókè láti máa gbé iṣẹ́ wọn kà. Àwọn ilé-iṣẹ́ àṣẹ fíìmù bí i Scene One production, Mainframe, Odunlade Adekola films production, Cooperate films àti àwọn yòókù máa ń gbé eré tó ní í se pẹ̀lú ètò ọrọ̀-ajé jáde, ètò-ẹ̀kọ́, ètò-ìṣèlú, ìbára-ẹni-gbépọ̀, Ìmọ̀ Sáyẹ́nsì àti ìmọ̀ ẹ̀rọ Ìgbàlódé. Ohun tí ó máa ń wà lọ́kàn àyà wọn ní bí wọn ṣe fẹ́ máa tọ́ àwọn òǹwòran sọ́nà nípa ohun tí ó yẹ kí wọ́n mọ̀ láti lè máa kó ipa tí ó bá tọ́ láwùjọ. Fíìmù Yorùbá, máa ń sábà tẹpẹlẹ mọ́ pé ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan ni ó ní ipa tí ó gbọ́dọ̀ máa kó láwùjọ.

Ọ̀nà ìdàgbàsókè orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ fíìmù iléese Mainframe máa ń tọ́ka sí. Ibrahim (2022). Àwọn fíìmù iléese yìí máa ń tọ́ka sí í pé àgbájọ ọwọ ni a gbọ́dọ̀ máa fi sọya. Láti orí fíìmù wọn àkọ́kọ́ ti wọn pè ní ***Ti Olúwa nilẹ̀***, wọ́n sàfihàn pé olórí ìlú ṣe pàtàkì. Ọba Alápátirá jẹ́ aṣáájú rere, gbogbo ọ̀nà tí ìlọsíwájú yóò fi bá ìlú rẹ̀ ni ó wà ní oókan àya rẹ̀. Fíìmù yìí safihan àwọn ẹ̀dá ìtàn kọ̀ọ̀kan nínú ahunpọ̀ ìtàn fíìmù náà pé, ipa ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan ni ó máa ń bí ìdàgbàsókè tí ó yẹ. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, ọ̀tún ìlú náà jẹ́ oníjẹkújẹ àti àwọn èniyàn kan, ó hàn gbangba pé, ọba tí ó jẹ olórí ìlú fi ẹsẹ̀ múlẹ̀ pé òtítọ́ ni ó gbọ́dọ̀ lékè. Ọba yìí ń fẹ́ ìlọsíwájú fún ìlú rẹ̀, gbogbo ọ̀nà ni ó fi ń wá bí ìlú òun yóò ṣe ni ìlọsíwájú fún ìgbéga ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan àti orílẹ̀-èdè wọn. Àrokò ni wọ́n fi ìtàn inú fíìmù yìí pa fún orílẹ̀-èdè Nàìjíríà, pé a gbọdọ̀ ní olórí tí ó ní àfojúsùn tí ó dára, kí orílẹ̀-èdè yìí, lè ní ìlọsíwájú, gẹ́gẹ́ bí ọkàn lára orílẹ̀-èdè tí ó ń gòkè àgbà lágbàáyé. Ó hàn nínú fíìmù yìí pé, dídá iléese sílẹ̀ nínú ìlú ṣe pàtàkì, àti pé àwọn olórí ò gbọ́dọ̀ máa gba àbẹ̀tẹ́lẹ̀ lọ́wọ́ àwọn ti ó fẹ́ dá iṣẹ́ sílẹ̀ nínú ìlú, kí àmúgbòòrò lè wáyé fún àwọn ará ìlú àti ìlú.

## ÌLÒ FÍÌMÙ YORÙBÁ LÁTI TÁN ÌSÒRO ORÍLẸ̀-ÈDÈ FÚN ÌDÀGBÀSÓKÈ

Iṣẹ́ ọnà jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì tí àwùjọ fi máa ń gbòòrò lóore koore, èyí tí ó máa ń bí ìdàgbàsókè (Olatunji 2020) arogun àti àròjinlẹ̀ ni a fi ń gbé iṣẹ́ ọ̀nà kalẹ̀ (adebowale 2019) ìṣe ọ̀nà kí i dédé wáyé lai jẹ́ pé ó ní ìṣe kan pàtàkì tí wọ́n fẹ́ fi rán sí àwọn òsùnsùn afọ̀ wọn. Fájẹ́nyọ̀ (2022) lítíréṣọ̀ ni iṣẹ́ pàtàkì tí wọ́n fí ń jẹ́ láwùjọ. Lítíréṣọ̀ yálà ìtàn àròsọ, ère Oníṣẹ́ tàbí wá fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìdánilárayá, èyí ti o gbọ́dọ̀ tọ́ka ìdàgbàsókè fún àwọn èniyàn àwùjọ. Wahab (2022). Adéoyè (1980) tọ́ka pé, iṣẹ́-ọ̀nà aláwòmọ lítíréṣọ̀ máa ń ṣe atọ́kùn ìdàgbàsókè fún àwùjọ. Omi Ọgbọ́n àwùjọ ni lítíréṣọ̀ jẹ́, lítíréṣọ̀ máa ń ṣàmúlò ìṣèlẹ̀ àwùjọ láti fi ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn èniyàn àwùjọ kí àtúnṣe lè wà láwùjọ. Olaitan (2021) lítíréṣọ̀ máa ń ṣàmúlò, oyè, ìrírí, àti ìṣèlẹ̀ fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìdánilárayá.

Fíìmù gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà lítíréṣọ̀ ní ipa pàtàkì tí ó ń kó láwùjọ wa. Ẹ̀yà lítíréṣọ̀ yìí ni àwọn ará ìlú ń sàmúlò ju báyìí. Kò fẹ́ ẹ̀ ẹ́ sí ọ̀wọ́ àwùjọ kan báyìí tí

kì í wo fìímù. Fíìmù Yorùbá ti di èyí tí gbogbo àgbáyé ń wo báyìí látàrí àgbékalẹ̀ wọn. Fíìmù Yorùbá ti di igi àlọ́yè báyìí. Àwọn òǹsefíìmù sì ń lò ó fún ìtọ́sọ́nà àwùjọ. Wọ́n ń lo fún ìtanilólobó, ìpè àkíyèsí sí, ìtọ́sọ́nà àti imú gbòòrò làákàyè ẹ̀dá. Oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni àwọn onifiimu Yorùbá ń gbé lo fìímù láti tán ìṣòro orílẹ̀ èdè. Ọ̀pọ̀ ìṣòro tí Nàìjíríà ń kojú lóníí, ni a lè fi fíìmù yanjú. Òye tí ó yẹ kí àwọn ọmọ orílẹ̀-èdè yẹ kí wọ́n ní, ni àwọn òṣèré gbọ́dọ̀ máa fi yé wọn, nípa ètò ìṣèlẹ̀, ètò ọ̀rọ̀ ajé àti ètò ẹ̀kọ́.

## TÍTÁN ÌṢÒRO Ọ̀RỌ̀ ÌṢÈLÚ

Fíìmù Yorùbá ti àwọn onífíìmù ń gbé jáde pẹ̀lú èròǹgbà láti wá ojútùú sí pákáǹleke ètò ìsèlú, èyí tí orílẹ̀-èdè yìí ń kojú láti ìgbà tí a ti gba òmìnira. Àwọn àjọṣe òṣèré onílànà Ògúǹdé ń ṣe gudugudu méje àti yàáyà mẹ́fà láti rí i pé àwọn ènìyàn mọ̀ nípa eto-ìṣèlú, ipa tí ó yẹ kí wọ́n kó, irú àwọn tí ó yẹ kí wọ́n yàn sípò láti orí káńsélọ̀, alága ìbílẹ̀, Gómìnà, àwọn asojú, àwọn asòfin àti olórí orílẹ̀-èdè. Àwọn onífíìmù ń lo fíìmù wọn láti máa tọ́ àwọn òṣèlú fíìmù wọn ṣọ́nà nípa àwọn tí ó yẹ kí wọ́n máa lò gẹ́gẹ́ bí alákòóso ẹ̀ka kọ̀ọ̀kan, èyí tí yóò jẹ́ kí ìdàgbàsókè ó wà. Fíìmù ***Alága káńsù*** tí ajílẹ́yẹ gbé jáde sàfihàn, ọ̀nà tí a fi lè ṣèlú, tí yóò bí í ìdàgbàsókè. Ajílẹ́yẹ sàfihàn ewu tí ó wà nínú yíyàn, àwọn olè, ọ̀jẹ̀lú, jegúdújẹra, wọ̀bìà sípò. Ó tọ́ka nínú fíìmù náà pé, olórí tí ó bá dára, yóò rí ìpọ́njú, ṣùgbọ́n adùn ni yóò kẹ́yin, ewúro. Fíìmù ***Àkọ́bí Gómìnà***, safihan ayé aláratá tí àwọn ọmọ Gómìnà àti àwọn olóṣèlú máa ń jẹ́ ní orílẹ̀-èdè yìí. Ó lo fíìmù náà láti tọ àwọn oṣélù sọ́nà, bákan náà ni ó ń pe àkíyèsí àwọn ará ìlú sí ọ̀nà tí wọ́n lè gbà, láti gba ara wọn silẹ̀ lọ́wọ́ àwọn ọ̀jẹ̀lu tí wọ́n pe ara wọn ní olóṣèlú.

***Agogo Èèwọ̀*** tí ilé-isẹ́ Túndé Kèlání Mainframe gbé jáde jẹ́ Fíìmù tí ó sàfihàn pé, ìṣẹ̀ṣe ṣe pàtàkì, tí a bá fẹ́ kí àwọn olóṣèlú kó ara wọn ní ìjánu. Ọ̀nà tí àwọn ará ìlú lè kópa tí ó yẹ, nípa dídẹ́kun àwọn ọ̀jẹ̀lú jẹ́ ìdánilẹ́kọ̀ọ́ pàtàkì tí òǹkòtàn fíìmù yìí gbé fíìmù yìí ka.

***Gang of Lagos***, ***king of boys*** ti Tóbi Bákàrè àti Sọ́la Sóbọ̀wálé ṣe isafihan àwọn olóṣèlú àti irú ìwà ọwọ wọn. Àwọn fíìmù méjèèjì yìí fi àwùjọ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà hàn. Irú àwọn tí wọ́n ń sèlú wá àti irú àwọn tí wọ́n ń sèlú lé lórí. Àhunpọ̀ ìtàn àwọn fíìmù ajẹmọ́-ìṣèlú ni àwon fíìmù tí àwọn onífíìmù máa ń lò láti fi ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ láti bọ nínú wàhálà ọ̀nà ìṣèlú ni orílẹ̀-èdè yìí. Àwọn fíìmù tí wọ́n tí fi ṣe ìsínijẹ ní àárin yìí ni wọ́n ń gbìyànjú láti fi tán ìṣòro yìí, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, ìṣòro yìí sí wa láwùjọ, síbẹ̀, àwọn ènìyàn àwùjọ tí ń ní òye kíkún nípa àwọn tí o yẹ kí wọ́n máa yàn sípò. Ojúṣe àwọn tí a yàn sípò àti àjọṣepọ̀ tí ó yẹ kí ó wà láàárin àwọn òṣèlú àti àwọn tí wọ́n ń sèlú lé lórí. Fíìmù ***Àṣírí Gómìnà*** (2003) tí Dúró jaiye Ìṣọ̀lá gbé jáde. ***Saworoidẹ*** (1999) Túndé Kèlání. ***Gómìnà*** Ọdúnladé Adékọ́lá (2019), Adelé Bíḿbọ́ Ọsìn (2018), àti ***Àlùmọ́nì*** tí Wùnmí Ọlábímtán náà gbé jáde ní ọdún (2019). Ọ̀pọ̀lọpọ̀ fíìmù ajẹmọ́-ìṣèlú ni wọ́n máa ń fi ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ nípa bí a ṣe lè tán ìṣòro ọ̀rọ̀ ìṣèlú ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà.

## ÌLO FÍÌMÙ FÚN TÍTÀN ÌṢÒRO ÈTÒ Ọ̀RỌ̀ AJÉ

Lára ìṣòro tí orílẹ̀-èdè ń kojú lágbàáyé ni ètò ọrọ̀-ajé tí polúkúmusu. Ọkàn lára orílẹ̀ èdè tí ó burú jàì ni ilẹ̀ Nàìjíríà. Láti lè wá ojútùú sì ìṣòro yìí ni àwon onífíìmù ṣe gbé àwọn iṣẹ́-ọ̀nà wọn kan ọ̀nà àbáyọ fún àwùjọ wa, tí ó bá jẹ́ pé àwọn Alákòóso ètò ọrọ̀-

ayé àti àwọn olóṣèlú kọbiara sí í. Bákan náà ni àwọn fíìmù tí a fẹ́ tọ́ka sí náà ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún ẹ̀dá àwùjọ kọ̀ọ̀kan láti lè rí tajé ṣe. Lítíréṣọ̀, pàápàá eré-oníṣe máa ń ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ rẹ̀ lọ́nà tààrà, èròǹgbà àwọn fíìmù bẹ́ẹ̀ ni láti là ọ̀nà fún ìdàgbàsókè ẹ̀dá àwùjọ tí ó bá níye láti ṣàmúlò ẹ̀kọ́ tí fíìmù bẹ́ẹ̀ bá ń kọ òǹwòran. Nínú fíìmù, ***Sàámú Alájọ***, Odunlade Adekola, gbiyànjú láti jẹ́ kí àwọn òǹwòran, rí i pé, àtẹ́lẹwọ́ ẹni, kì í tannijẹ, àti pé, iṣẹ́ ẹni ni iṣẹ́ ẹni, ẹ̀dá kò gbọ́dọ̀ máa tijú iṣẹ́ rẹ̀ nígbà kankan. Ìtàn inú àhunpọ̀ ìtàn fíìmù náà jẹ́ kí á mọ̀ pé, ìṣun tẹ́rẹ́, tẹ́rẹ́ ní í dibú.

Fíìmù ***Àlùmọ́ni*** láti ọwọ Wùnmí Ọlábímtán tan ìmọ́lẹ̀ sí rúkèrúdò ètò ọrọ̀-ajé láwùjọ. Ó sàfihàn, àwọn ohun àmúsọrọ̀ tí ó lè jẹ́ kí àwùjọ ni ìlọsíwájú, tí àwọn adarí bá ló àwọn ọ̀rọ̀ tí Olódùmarè fi jíǹkí orílẹ̀-èdè. Fíìmù ***Ọrọ̀-ajé*** tí Lateef Adédiméjì náà gbé jáde ní ọdún (2018) náà kò sai tọ́ka sí ọ̀nà tí fíìmù ń gbá wá ojútùú sì ìṣòro orílẹ̀-èdè. ***Lisabi*** tí Lateef adedimeji gbé jáde náà fihàn pé iṣẹ́ ní lani. Lisabí gẹ́gẹ́ bí olórí kan nínú fíìmù náà, tẹpẹlẹ mọ́-ọn fún gbogbo àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ pé, iṣẹ́ ṣe pàtàkì fún ìtẹ́síwajú ẹ̀dá. Bákan náà ni ó fi yé ni pé, kò sí bí ètò ọrọ̀-ajé ṣe lè gbòòrò lái jẹ́ pé àwọn ẹ̀dá àwùjọ sapá gidigidi láti rí i pé àwọn náà dá ilé-iṣẹ́ síṣe sílẹ̀. Ó tọ́ka pé, ọ̀lẹ ò le è ráyé wa. Ìgbìyànjú tí àwọn Ọ̀dọ́ àwùjọ bá ń ṣe máa ń ní í ṣe pẹ̀lú ìdàgbàsókè àwùjọ wọn. Fíìmù Yorùbá sábà máa ń kọ́ àwọn ẹ̀dá àwùjọ pé káràkátà ṣe pàtàkì, bákan náà ni pé ètò pàtàkì gbọ́dọ̀ wà fun ètò ọrọ̀-ajé kí ó lè rú gógó fún igbé-ayé-gbádùn àwọn ará ìlú. Fíìmù ***Ṣaworoidẹ***, Túndé Kèlání safihan, ọ̀nà ti ètò ọrọ̀-ajé ìlú lè gba wúlò fún ìdàgbàsókè àwùjọ, ó tọ́ka pé owó tí ó bá ń wọlé sí àpò ìjọba, gbọdọ̀ wúlò fún ìdàgbàsókè, kì í ṣe pé kí àwọn kan máa kó owó sápò. Ó tẹpẹlẹ mọ́-ọn pé àwọn ọ̀dọ́ ní ipa pàtàkì láti kó lórí kí ètò ọrọ̀-ajé ìlú kẹ́ṣẹ̀járí.

Oríṣìíríṣìí fíìmù Yorùbá safihan ọ̀nà tí ètò ọrọ̀-ajé àwùjọ gbà ṣe pàtàkì fún àwùjọ. Ohun tí ọ̀pọ̀ fíìmù máa ń tẹpẹlẹ mọ́ ni pé, àwọn òṣìṣẹ́ gbọdọ̀ máa sapá wọn ní gbogbo ọ́fíìsì tí wọ́n bá wà. Pàtàkì àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba lórí ìdàgbàsókè ètò ọrọ̀-ajé láwùjọ ni fíìmù ***Àbẹ̀ní*** Mainframe náà tọ́ka sí. Ó hàn gbangba pé àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba gbọdọ̀ máa ṣe ojúṣe wọn,láti rí i pé, ètò ọrọ̀-ajé ní ìlọsíwájú.

## FÍÌMÙ FÚN TÍTÀN ÌṢÒRO ÌMỌ̀-Ẹ̀RỌ

Ìmọ̀-ẹ̀rọ ṣe pàtàkì fún ìdàgbàsókè àwùjọ kọ̀ọ̀kan. Kò sí bí orílẹ̀-èdè kan ṣe lè gòkè àgbà, tí ìmọ̀ ẹ̀rọ orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ ò bá ní ìlọsíwájú Ọ̀síyẹmí (2021). Ohun ìwúrí ni ó máa ń jẹ́ fún àwọn adarí ìlú, tí ìmọ̀-ẹ̀rọ ìlú bẹ́ẹ̀ bá ń lọ geere. Nínú àwọn fíìmù àgbéléwò, wọ́n máa ń ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ lórí pàtàkì ìmọ̀-ẹ̀rọ. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ fíìmù ni wọ́n máa ń lò láti jẹ́ kí á mọ̀ pé ìmọ̀-ẹ̀rọ ṣe pàtàkì fún ìdàgbàsókè orílẹ̀- èdè. ***Tribe Call Judah*** tí Fúnkẹ́ Akíńdélé ṣe, safihan pàtàkì ìmọ̀-ẹ̀rọ láwùjọ. Ó hàn pé lái ṣe ìmọ̀-ẹ̀rọ, àwùjọ kò le è ní ìlọsíwájú. ***She must be obey***, Fúnkẹ́ Akíndélé, ***Ìjàkùnmọ̀*** Toyin Aimaku fọnrere pàtàkì ìmọ̀-ẹ̀rọ láwùjọ. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn fíìmù Yorùbá ni wọn máa ń ṣàmúlò ìmọ̀- ẹ̀rọ láti lè jẹ́ kí àwọn ènìyàn ó ri pé, fíìmù Yorùbá kò dúró ṣojú kan àti pé, yíyí tí ayé ń yí, ìmọ̀- ẹ̀rọ kó ipa pàtàkì nínú rẹ̀. Àwọn ohun ọ̀tun tí ó máa ń tọ́ka sí ibi ẹ̀rọ àti ìmọ̀-ẹ̀rọ ni wọ́n máa ń ṣàmúlò nínú àwọn fíìmù Yorùbá.

## TÍTÀN ÌṢÒRO ÌBÁRA-ẸNI-GBÉPỌ̀

Oríṣìíríṣìí fíìmù Yorùbá ni wọ́n máa ń lò láti sàfihàn ọ̀nà láti fi ìfẹ́ bá ara wa gbé. Àjọgbé ṣe

pàtàkì láwùjọ Ajíbádé (2016) àwọn ẹ̀dá àwùjọ gbọdọ̀ máa wà ní ìrẹ́pọ̀ tí wọ́n bá fẹ́ kí ìdàgbàsókè ó wà ní àwùjọ wọn Ajétúnmọbí (2019) fiimu Yorùbá sábà máa ń tọ́ka sí i pé, Ìbára-ẹni-gbépọ̀ ṣe pàtàkì tí a bá fẹ́ kí àwùjọ ní ìlọsíwájú. Fíìmù ***The Tribe Call Judah*** Funke Akindele, fi pàtàkì ìrẹ́pọ̀ hàn. Kò sí ìwúlò iṣẹ́-ọnà tàbí isẹ́ lítíréṣọ̀ kan, tí kò bá ti wúlò fún àjọgbé tí ó lóòòrìn. Ó ṣe pàtàkì kí àwọn ènìyàn àwùjọ máa gbé ní ìrẹ́pọ̀, èyí ni ó máa ń ṣokùnfà ìdàgbàsókè, tí fíìmù Yorùbá ó bá máa kọ àwọn ènìyàn lẹ́kọ̀ọ́, ó se é ṣe kí àwùjọ ò máa ṣe é gbé. Fíìmù ***Adébímpé ọmọ ọba*** tí Bímpé Oyebade ṣe, tẹpẹlẹ láti mọ̀ pé, àwùjọ gbọdọ̀ gbà pé, kò gbọdọ̀ sí ẹlẹ́yà- mẹ̀yà àti pé, ọkàn náà ni gbogbo wa, ì bá à jẹ́ olówó, Mẹ̀kúnnù, Ahúsá, Ígbò tàbí ẹ̀yà yòówù kí ó jẹ́ káàkiri orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Àwọn fíìmù Túndé Kèlání bí i ***Ṣaworoidẹ, Àbèní, Agogo Èèwọ̀*** àti ***Narrow path*** náà tẹpẹlẹ mọ́-ọn pé Àjọgbé ṣe pàtàkì nínú ìdàgbàsókè orílè-èdè.

Fíìmù ***Arugba***, Tunde Kelani safihan Ìbára-ẹni-gbépọ̀ tí ó yanrantí. Ó sàfihàn pé kò gbọdọ̀ sí ẹlẹ́yà-mẹ̀yà ẹ̀ṣin, èdè tàbí ìlú, tí a bá fẹ́ kí ìlọsíwájú ó bá orílẹ̀-èdè. Iṣẹ́-ọnà gbọ́dọ̀ lè tún àwùjọ ṣe. Lítíréṣọ̀ máa ń jẹ́ kí àṣà àti ìṣe àwùjọ ó gbòòrò, kí ó sì ní ìlọsíwájú, èyí tí ó máa ń han lára àwọn ẹ̀dá àwùjọ tí wọ́n sábà máa ń jẹ́ òǹwòran àwọn fíìmù yìí

**IṢẸ́ TÍ FÍÌMÙ GBỌDỌ̀ MÁA ṢE LÁWÙJỌ**

Fíìmù káríayé wà fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìdánilárayá Ibrahim (2022:48) gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà lítíréṣọ̀, fíìmù gbọ́dọ̀ lè máa tọ àwọn ènìyàn àwùjọ sọ́nà, kí àwùjọ lè ṣe é gbé, fún wọn Akínbòdé (2023) ipa tí fíìmù Yorùbá ń kó, kò ṣe é fi ọwọ́ rọ́ sẹ́yìn. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn òǹwòran ni wọ́n máa ń ní ìmọ̀sílára nípa àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ inú fíìmù tí wọ́n ń wò, àwọn ẹ̀dá àwùjọ a tiẹ̀ máa barajẹ́ lọ́pọ̀ ìgbà tí wọ́n bá wo Eré-oníṣe tí a kà sínú fọ́nrán Adélékè (2018) ó han gbangba pé tí a bá lo fíìmù bí o ti yẹ àyípadà tí ó lóòòrìn yóò wà ní àwùjọ wa. Lóde òní àwọn ènìyàn kò ní ìgbẹ́kẹ̀lé lórí àwọn ọ̀rọ̀ aṣáájú ìlú, olóṣèlú ìwàásù tàbí wáàsí, ṣùgbọ́n wọ́n sábà máa ń fẹ́ àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí àwọn onífíìmù bá ń ṣe nínú àgbékalẹ̀ wọn. Fíìmù gbọdọ̀ máa tọ́ka sí àwọn ohun tí yóò jẹ́ kí ayé ó rọrùn fún tọmọdé-tàgbà. Fíìmù Yorùbá gbọ́dọ̀ máa fọnrere àwọn ọ̀nà ìdàgbàsókè ẹ̀dá àwùjọ kọ̀ọ̀kan àti àwùjọ fúnra rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́-ọnà, fíìmù gbọdọ̀ lè máa fa àwọn òǹwòran mọ́ra lórí bí ó ṣe yẹ kí wọ́n ó máa kópa ribiribi láti ṣe àtúnṣe àwọn kùdìẹ̀-kudiẹ àwùjọ wọn. Ojúṣe àwọn onífíìmù ni láti máa ni lọ́kàn àyà wọn pé, ọ̀nà àti wá ojútùú sí ìṣòro àwùjọ ni isẹ́ àwọn dálé lórí, kì í ṣe kí wọ́n kàn máa gbé fíìmù jáde, nítorí pé wọ́n fẹ́ pa owó, tàbí fún awẹ́wàá nìkan.

**ÌKÁDÌÍ**

Ọ̀nà àti tán ìṣòro àwùjọ ni ó gbọ́dọ̀ máa wà ní oókan àyà gbogbo Oníṣe ọ̀nà atinuda. Lítíréṣọ̀ ni ipá pàtàkì tí ó ń kó lórí ìdàgbàsókè àwùjọ. Àwọn àjọ òṣèré tí wọ́n ń gbé fíìmù jáde gbọ́dọ̀ lé máa gbé fíìmù tí yóò máa tọ́ àwọn ènìyàn sọ́nà nípa, ọ̀nà ìgbé-ayé, àjọgbé àti ìwà ọmọlúwàbí. Títán ìṣòro àwùjọ ṣe pàtàkì fún àwọn onífíìmù ,wọ́n gbọdọ̀ gbìyànjú láti máa tún àwùjọ ṣe, kí ìgbé-ayé lè rọrùn fún àwọn tí wọ́n nífẹ̀ẹ́ wọn, tí wọn ń wo àwọn fọ́nrán fíìmù wọn.

**ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ**

Adédèjì, J.A. (1967). *'The Alárìnjó Theatre: The Study of Yorùbá theatrical art from its earlist beginnings to the present times'*

Ph.D. Thesis, Ìbadàn. University of Ìbàdàn.

Adéjùmọ̀, A. (2014). Grass-Roots Movement and Propagation of Indigenous Culture in Akínwùmí Ìṣọ̀lá's Selected Plays" nínú YORÙBÁ: *Journal of Yorùbá Studies Association of Nigeria*, (7). 3 pp. 60-86.

Adélékè, D. (1995). *"Audience Reception of Yorùbá Films"*. Ph.D. Thesis, Ìbadàn. University of Ìbàdàn.

Adéoyè, C.L. (1979). *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá*. Ìbadàn. Oxford University Press.

Àkàngbé, C.A (2005). *"From the stage to Motion Pictures: The Changing Phases of Lérè Pàímọ̀ Theatre"*. Unpublished M.A Thesis, Ìbadàn: University of Ìbàdàn.

Ajíbádé G.O. (2009) *Finding Female voice: A socio cultural Appraizal of Yoruba Nuptical Poetry.* Koln: Rudiger Koppeverlag.

Beier ati Gbadamọsi B (1959). *Yorùbá Poetry*. Ìbàdàn: Government printers

Clark, Ẹ̀bùn (1979). *Hubert Ògúndé: The Making of Nigerian Theatre*. Ìbadàn, University Press PLC.

Dáramọ̀lá O àti Jéjé, A (1967). Àwọn Àsà àti Òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá, Ìbàdàn: oníbọnòjé press.

Ládelé, T.A.A (1986). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Lagos: Macmillan Nig. Publishers.

Ògunbà, Oyin (1967). "The Theatre in Nigeria" nínú *Prescence Africaine*, pp. 65-88.

Ògúnbíyì, Y. (ed.) (1981). *Drama and Theatre in Nigeria: A Critical Source Book*. Lagos Magazine Special Publication, Federal Ministry of Social Development, Youths, Sports and Culture.

Ògúndèjì, P.A (1981). *"The Plays of Oyin Adéjọbí*: An Introduction". Unpublished M.A. Thesis. Ìbadàn. University of Ìbàdàn.

Ògúndèjì, P.A (2014). *Yorùbá Drama in Time Perspectives*. Inaugural Lecture, University of Ìbàdàn.

Ọlájubù, I.O. (1970). *"Iwì Egúngún Chants in Yorùbá Oral Literature"* M.A. Thesis, Lagos: University of Lagos.

Ọlátúnjí, O. (1984). *Fearures of Yorùbá Oral Poetry*. Ìbàdàn: O.U.P

Orímóògùnjẹ, O. C. (1996). *Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá*, Lagos: Káróhunwí Nigeria Enterprises.

Ọ̀pádọ̀tun, O. (2003). *Òǹkọ̀wé àti ìwé-kíkọ Alátinúdá.* Ọ̀yọ́: Odumatt press & publishers

Oyèdélé, M. (2020). *Portaryal of Female Gender in the Literary works of Diméjì Ajíkòbí.* M.A Thesis department of Linguistics, African and Asian studies university of Lagos